**Owe**

KITA-KITA KOMỌ TI ARISIKI, KI A ŞIŞẸ BI ẸRU KO DA NKAN

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ŞE WI LẸJỌ

**Asoje**

ENIA TI IYA KOSI T... JẸ S'ỌMỌ ỌLỌMỌ LORE

VOL. XIII No 101 LAGOS. SATURDAY AUGUST 5, — AUGUST 11, 1961. KOBỌ MEJI (2D)

# OLOPA MU ENIA MEFA FUN ESUN ADAMODI IWE OWO AIYEDERU L'ABEOKUTA

ABẸOKUTA - Irohin gẹgẹbi ọwọ awọn ọlọpa-inu ti ṣe lọ ka enia mẹfa nọ inu ile kan nibiti nwọn ti ntẹ iwe owo aiyederu nilu Abẹokuta ni Saji Ọlọpa-inu kan sọ fun adajọ Kotu ni Abẹokuta, ni ilẹ Iwọ-orun Nigeria.

Saji James Kodaolu ni o njẹri niwaju adajọ agba ti Kotu kekere ngbati nwọn nṣe iwadi ẹsun iwe owo ejidin-logoji-le-lẹgbẹrin şile mẹwa mẹwa, mẹtadin-logun ponun kokan ti o jẹ iwe owo aiyederu ati awọn irinṣẹ ti nwọn fi ntẹwe owo ti nwọn fi enia mẹfa sun.

Saji Kodaolu sọ fun adajọ wipe ni ọjọ kokandin-logbọn oşu April ni ọdun yi, on ri awọn Frederick Osholemi, Ashimi Durojaiye, Ishola Alabi, Ayinla Ọbajinmi, F. Raufu Ayinla ati Justice Amosu ninu ile kan nibiti nwọn ti ntẹ iwe owo aiyederu.

O sọ pe Ọlọpa ti gbọ laşiri pe nwọn tẹ iwe owo aiyederu ninu ile kan. lori eyi ni on ati awọn ọlọpa-inu mejọ lọ yi ile na ka ni Iporo Ake, Abẹokuta nibiti awọn ti sọ wipe nwọn ntẹ iwe owo adamọdi na

Şaji Kodaolu sọ pe on mu awọn miran ninu awọn ọdaran na pelu irin'şẹ ti nwọn fi ntẹ owo, lẹhinti awọn si tu ile na wo, awọn ri awọn iwe owo aiyederu gba ati awọn nkan ti awọn ayaworan nlo.

Awọn mẹfẹfa ran'ri pe ko jẹbẹ, irọ ni. Nwọn şi ngbọ ẹjọ na lọwọ.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA ILARO, BENIN-CITY, WARRI SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.
Telephone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbanliger London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK. PARIS HAMBURG.

## Olotu Ijoba Nigeria J'oye "Bobajiro" Nilu Oyinbo.

LONDON - Olotu Ijọba Apapọ ti ilẹ Nigeria Ọla Alhaji Sir Abubaker Tafawa Balewa ni Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo, Eliza eth Keji fi Oye rla "Bọbajiro" (Queen's Privy Council) da lọla ni kete ti Olotu ijọba gunlẹ si ilu Oyinbo lati ilẹ Amẹrika ti o ti lọ fi ọjọ mejọ şe abẹwo rẹ.



ALHAJI DR. SIR ABUBAKAR P. C.

Ki Olotu ijọba to wọkọ Ofurufu rẹ kuro nilẹ Amẹrika, o sọ fun awọn Oniwe Irohin wipe on gbadun inu rere pẹlu ifẹ ailabawọn ti Alakoso (President) ijọba ilu Amẹrika ni si ọrọ ilu awa enia dudu. O si fesi dabun si ibere wipe bi ilẹ Nigeria yio ba di ilu adase eyiti yio mu agbara Iselu kuro lọwọ ọba ti yio

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

### H'! ENYIN OBI, E R'OJU OLE BO MU? OMO NYIN KO SE AGBAFO O NKASO WALE

(Lati Owo Latifu Abiktunde)

Mo ki gbogbo yin papa ul ... ayin O kune ir lin Eeti - yofi, pin ni Olego ij aki ... O.okunrin eye l r. ile, mo t u de bi mo ti se nda !

Oro ... ti ... se yio e leri awo ... o wa iwa ... je ey ... Olorun ko le, ... won ... mba omo w n leri je, E yin obi enyin ni m ... mba wi l ni, ... o chi ... je ... hun jaa daje ... pe ... gba

( Wo yoku loju ewe ... )


*Always ask for*

**'DE FACTO'**

*the bread with the appetising flavour*


# AWON OLUKO GESI TI YIO WA KO AWON OLUKO NIGERIA



LONDON - Igbe ... ej Aseju ile Nigeria nilu Oyinbo, Ogbeni C. O. Omolo u ... ti e f ... awon Oluko omo Gesi ti o mbo wa fun awon Oluko ile Nigeria ... se eko ni ... onje ... onje ti St James laipe yi.

Awon Oluko marun le-ladota (55) ni awon mu ninu bi egbaa Oluko t ... f ... a, m d gun ninu awon Oluko na n yio se ira lowo fun a o Oluko ... g ga, Ogoji ni yio se iranlowo fun awon Oluko ile eko kekere.


**Plushes, Velvet, Velveteens, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, ( Faji Market )

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction ... Guaranteed


## Iwadi Banki Tun Di Agbeko Lori Eketa

EKO – Iwadi Banki ti won ti n se r gbodiyan re ni Kotu giga ti ile Eko ni Kotu tun gbe k ni ojo Monday ose yi, ko tile ni ojo ... yi ju wipe ki awon si lo da duro na lo.

Ogbeni Adajo Charles D. Onyeama so ninu Kotu giga wipe Ase iwadi na ti o f' ra ko ofin pataki r inu iwe eto ofin isolu wa Nigeria yi, nitori lo s waju Kotu ... ti ... Nigeria ki awon Adajo agba fi oka le.

L ya Ogbeni Dingle Foot Q.C. pelu Ogbeni Dick ... ti Oloye Akin-Olugbade l'o wa fun Oloye Bayo Doherty ti o ... ejo ati W. N. D. C nilu Ibadan ni o tun ta ... ase iwadi Banki na. Oloye ... R. A. Williams, Q. C Ogbeni Agbaje Williams a t i Ogbeni A ... egba l'o wa fun W. N. D. C.

Alabojuto idajo ati Alakoso ofin ilu ba Apapo e, Lokita T. O Elias Q. C. pelu Ogbeni S. D. Adebiyi ni o wa fun Olotu ijoba Apapo se

Ogbeni Gerald Impey ti ile ise Impey ati Burke ni o wa fun ... awon yan lati se iwadi Banki na, on ... ni o ... oro ni Kotu wipe awon metta ti o je Oluwadi ti ... Sir Vahe Bairamian, Adajo Kotu n'a julo ti ijoba Apapo se, Ogbeni Gerald Cooke ati Ogbeni James H ... on pe awon ko ni nken pelu iwadi Banki, awon ko si ni se iwadi na mo titi ti Kotu n'a yio fi f'oke le.

Ni'korina, Ogbeni Impey be Adajo ki o da awon Oluwadi sile kuro ninu ejo na gegebi olaye ti on se. Lehin ariyanjiyan ti awon Loya se ni Adajo bere lodo Alakoso ofin bi o ba tako oro Ogbeni Impey, o si dahun pe ... bedo r, mo bere f eji.

( Wo yoku loju ewe karun ) →

# BABA META NDU OMO KAN

EKO — O ti tẹ ọdun kan nisisiyi ti awọn ọkunrin mẹta ti ndu ọmọ t' binrin kan bi ti ọrọ na ko si ti l'oju ninu Ile ẹjọ t' ko-t'aya nilu Eko.

Ẹnikini ni Ọgbẹni Julius Ayẹni ti nṣiṣẹ akun-ọdà l'ọgba Reluwe ni Ebute-metta o sọ wipe iya ọmọ na Alakẹ Adelẹyẹ ni nwọn ti gbe ni yawo fun on lati ọdun mọkanla sẹhin, o si bimọ mẹrin fun on.

O tun sọ pe ninu oṣu June, 1259 ni iyawo on lọ si ile ni Ikọ'e Ekiti, ilẹ Iwọ-orun Nigeria, lati lọ bẹ awọn obi rẹ wo, nigbana, o si ti l'oyun. Nigbati o pada de, ko de s'ile Ọgbẹni Ayẹni, o lọ de si ọdọ enia rẹ kan, o si sọ fun Ayẹni pe ọmọ ti on ngbe kiri yi ki iṣe ti Ayẹni.

Ẹnikeji ti o tun ndu ọmọ na ni Ọgbẹni Ọlaiya ti Alakẹ ba nilu wọn nigbati o lọ sile.

Ẹnikẹta ti o tun kun wọn ni Ọgbẹni Aminu ti o nṣọ ẹnu-ọna fun awọn Bata Shoe ni Apapa, ọdọ rẹ ni Alakẹ wa ni 20, Opopo Ogidan, ni Mushin nisisiy. Alakẹ sọ wipe Aminu l'o ni ọmọ on.

Ọgbẹni Ayẹni sọ wipe ẹnikẹni ko si f'oruko rẹ gb'awe fun ọmọ na, Bayi ni Ọgbẹni Ayẹni ṣe kọwe si Ile iṣẹ ti nwọn ti ngb'awe ọmọ ati Ile iṣẹ ẹjọ t' kọ-t'aya ti sọ pe ki nwọn maṣe fun Alakẹ niwe ọmọ na.

Ọgbẹni Ayẹni sọ wipe nwọn ni awọn yio ṣe iwadi ọrọ na, lati nkan bi ọdun kan, on ko gbọ pan, on ko si gbọ mumọ.

## Oloye Akintola Ndabira!

IBADAN — Oloye S. L. Akintọla, Olotu ijọba Iwọ-orun ni nwọn fe ere bọlu af'ẹsẹgba ṣe iyesi re ni ale ọjọ Satide tokọja ni ibi iṣere gbangba-ṣeju ti nwọn npe ni "Liberty Stadium" nilu Ibadan.



Oru ọjọ Satide na dabi ọsan nigbati ina Lentiriki nkerin ni orişirişi awọ, awọn ọlọpa egbe agba-bọlu ti ilu Kaduna fi merinla bori ti Ibadan. Olotu ijọba ni nwọn fi ọla ẹbọ gba s'agbọ fun u.

Ọgbẹni V. A. Robinson ni Olutọju ere bọlu na.

## Ta lo le fesi ibere yi?

Ni Ilu kan onje won pọp, ni ojọ kan Okunrin kan wa onje lọ si ilu keji nigbati o de ilu keji, ko ri onjẹ ni o wa ri agbọ dọ erin meji o jẹ ọkan ninu rẹ, o ku ẹyọ erin kan, bẹẹ ni enia meji ko gbọdọ jẹ. Iya rẹ wa nile, Baba rẹ wa nile, Iyawo rẹ wa nile, ọmọ ti Iyawo bi fun Okunrin na wa nile, Aburo na tun wa ni ile pẹlu, nigbati o nduri bọ wa sile ni o pade okunrin kan loju ọna o wa sọ fun pe, ebi ti fẹrẹ pa awọn ile rẹ ku ni ile koda ti won ko ba ri onjẹ jẹ loni gbogbo awọn ni lati ku.

Ni o ba mura si irin re, bi o ti de ehin ile ni Iya sare pade rẹ, Baba sare pade re, Iyawo sare pade re, ọmọ rẹ na sare pade re. Bẹẹ erin yẹngẹn kan ṣoṣo yi, enia meji ko gbọdọ jẹ, bẹẹ eyi ti ko ba de jẹun ni ojọ na o ni ati ku ni.

Tani o yẹ ki o fun ninu awọn ti mẹrẹrin?

Emi ni, Amudu Irewọlede.

# AWON ONIMOTO BOLEKAJA DA ISE SILE

EKO — Ni ojo Monday ọsẹ yi ni gbogbo awon awamoto Bọlekaja lati Idi-Oro da iṣẹ sile lati owuro, o to ogota Bọlekaja ti ko ṣiṣẹ rara.

Rogbodiyan bẹrẹ lori iwe aṣẹ ti igbimo Ibile Eko (L. T. C.) fun won lati le wa'lu Eko, eyiti awon Onimoto Bolekaja so wipe eyo Iwe aṣẹ medogbon kere pupo, opolopo si ni kole wo igboro Eko. Igbimo ibile Eko so wipe ki ero ma ba po apoju ni awon fi ṣe be.

Ọgọgorun awon oṣiṣẹ ti nwọn ngbe Idi-Oro ati agbegbe Mushin ti o jẹ wipe Moto Bọlekaja ni nwọn nwọ lọ sibi iṣẹ won ni Eko, ni won ṣe lẹhin pupọ ki nwọn to debi iṣẹ won. Awọn ti ko ba won da iṣẹ silẹ ni nwọn nse idina fun, ti nwọn ko jẹki nwọn le koja.

Ayafi igbati ọkọ ẹru ala mẹta ko awọn ọlọpa de ibudo Moto ni Idi-Oro ti nwọn le awon to da iṣẹ silẹ na lọ.

# E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE LOSOSE

# ERU KOBA ODO - GBOGBO ARA NI IJA

Lati ọwọ
Prince J. A. Wusu Esq.

Ni ọjọ Akatakiti ti iṣe oṣu ọdun December, Boxing day 26th. 1925, labi Ọgbẹni wa Ẹrukobodo. Baba rẹ Ogboni A'agba Olori Ijọ Alufa Aladura n. Church Holly Face of Christ, ninu awọn ijọ ẹgbẹ baba nla ejila, eni ... ọpọlọpọ ọdun ni abẹ Marine Department lati 1908 titi di 1943 ti o fi gba isinmi, iya rẹ papa Ologbe ... o sun si ilẹ Oluwa ni oṣu 9th April 1961, ti o si gba 99 years laiye ki o to jẹ'pe Ọlọrun

Ki ... iya Olotu wa Eru kobo'do ki o daru si rere, ki Oluwa ... ọjọ baba Olotu wa, Ẹru-kobo'do siwaju, ski Baba wa Joseph A. Wasu oku apehinda, ti iy... iya Olotu wa Eru-kobo'do, ki apẹhinda Susanah Tanimowo Olele ... ọrọ ẹhin ti o fi sile l'ọrun towo-tomi ... Mr. Bandele Michael Odunewu, Victoria, Ibironke, Ọlaitewu. Sabaira, Omoyara Wusu pẹlu Olotu wa Prince Jonathan Abiọdun Wusu, Olori A'atako ẹgbẹ ... ọmọ ologun atijọ, ki Oluwa mulẹ dari fun ... ku ile ... o.

Aṣẹṣẹ ... Aka..., ni ọrọ emi Er...-kobo'do, ki ijọba Nigeria ... ohun rabirabi kan nṣẹlẹ ni (House of Representatives) ile igbimọ awọn Oṣelu Nigeria, eyi dabi eni ti edi on ọfun nmu, ki ẹ r aṣe jẹki awọn ... wa nigbati a ni a nwa Ominira ti a si tun fa ... ẹ ko ... wipe ọrọ nla mbọ? ti a ba ti ... ọrọ ... fun ara wa, mo si rope otitọ na ko ... ti arugbo ... suukun ... ẹpọlọpọ ti wọn mbẹru lati sọ ọrọ si iwe ikede, kaka ki wọn sọ ti ẹnu wọn, wọn ama pa itan, wọn ama pa alọ, wọn asi ma powe.

(Wo yoku loju ewe karun)


# OKU'JA WOLU

NIBGATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN EYI NI OGUNTI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Nyin
Sinu Iwe Irohin
ELETI-OFE



CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLD AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street, Lagos.

E mase fi omi so'o rara

Don't waste water



E bilo fun awon omode dada

## Iwadi Banki

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Ki ama b'ẹpo lọ sile Oloro mọ, Adajọ sọ w'pe on yio fi siwaju K ru nla julọ lati fi ajọ si ariyanjiyan wọn na, ki o to le mọ bi 'jọ na yio jẹ gbigbọ fun on.

## ERU KOBA ODO - GBOGBO ARA NI IJA

Lati ọwọ
Prince J. A. Wusu Esq.
(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

Ọrọ Nigeria ti kọja iyẹn ti ọkọmọ kan l'ẹṣoro konko l'awa ṣoju; bi awọn Minisita wa bi mọ pe ki ṣe ti ara wọn nikan ni wọn ndu atipe ti i ẹru ko si ni b,. em' Ẹru-kobo'do a idi alaṣeju bọ omi gbigbona ti m'i a sile de 'bo d di y n ti o bọ, ekiki ti jẹ bẹrẹ si ta siyin leti na, kanakana pa ọmọ ega ija mbọ ija koide, eṣe akole bẹr i ori ti ki a fi fila de idi, awa ni ẹgbẹ Y.N.P.C. (Yoruba National Congress Party) nitoripe a ti ri ọpọlọpọ baba nla iy lẹnu pe ki a ko irọ kuro, ki a ma sọ ọrọ didun, ct tọ san ju irọ lọ, eṣe ti a fi yọ ọmọ loko ẹru ti yio si tun p da ju baba rẹ lọ? eyi ko le ṣeṣe n'toripe N.C.N.C. ati Action Group ko le wọlọ lailai ni l Hausa, sugbọn Hausa gbagbe olore wipe obe tutu ni adamu nbula, sugbọn bi ko ba si ti Yoruba ati Ibo iran Hausa ko le jẹ Minisita lailai.

## OKỌ WA NHE OLE KO NILẸ!

Port-Harcourt - Ni ọjọ Satide ti o kọja ni Ọgbẹni David Akoredelu, akọ e ẹgbẹ awọn osiṣẹ Nigeria Motor Transport, o lọ si lu Aba lọ sọ eto owo awọn ẹgbẹ re ni owurọ, o si pada si ile re n 18, Lagos Street Port-Harcourt ni dede ag go kan ọsan l s oye Amodi lara rẹ.

La pẹ pupọ ni iyawo rẹ ti oyun wa ninu rẹ pada de lati ọja ti o ti lọ o si ba ọkọ rẹ ti o pada nilẹ pẹlu ifura, ko tilẹ le sọrọ, ni nṣọn ba gbe lọ si Ile- Iwosan ni nwọn ba gbe ku si ni ọjọ sẹ. Ikurẹ mu fura dani nitorina nwọn gbe si ile ayewo awọn oku, (Mortuary)

Awọn ebi ati iyawo re wa ninu ibanuje ofo ilu re laiti gbe oku re lo sin, ni awọn ole wole re lọ ko gbogbo eru ol gbe ne. Ọgbẹni Akorede fi iyawo re ti o loyun ati omo meji sile, okunrin kan ati obinrin kan.

## E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE LOSOSE

## AWON OMO AKEKO NILU OYINBO



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ akẹkọ ti ẹgbẹ Alagbelebu Pupa ti fawọn lọ kọṣẹ iranlọwọ pajawiri bi jamba ba ṣẹlẹ nilu Oyinbo.
Awọn mẹta ti a nwo niwaju nfi ise han awọn ti o duro gẹgebi nwọn nti fi ise di ibiti ena ba fi pa tabi ti o fi gb'ọgbẹ.

### HA! ẸNYIN OBI, Ẹ ROJU OLE Ẹ O MU?

(O bẹrẹ loju ewe keji)

aye fun omọ rẹ, ti omo re nko iso oriṣiriṣi olowo yebiye ole ti ko bere ibiti o ti ri ti o si wo iri n ti o tun ngba owo lowo omo re nigbati o je pe dele lo yi nlo.

Mo bẹ ẹnyin obi ti o ba tha irufe awon iwa bayi ki o jowo ki o ronu piwada lati ma ba awon dara fun won, ekeda won ni y'o ma fi yin sese Ti e ba ti ri iwa ti ko to ejowo, e ma ba won wi, e ye jeki nwon ma ko asokaso wale tabi ki e ma igba owo lowo wen.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

. . . Created by world's top Artists in a wide variety of colours . . . and if your problem




is a Carpet to match we have the answer. Twenty-five plain colours and many more in floral and Persian Designs.

**LEVENTIS**
DEPARTMENT STORE,
MARINA

## Olotu Ijọba Nigeria J'oye Boba Jiroro

(O bẹrẹ loju ewe kinni

di ti awọn ti ilu yan (Republic) yio jẹ ifẹ inu awọn ara ilu.

Olotu ijọba ati awọn ẹmẹwa rẹ ti o ba lọ yio pada de silu Eko ni ọjọ ọsẹ (Sunday) gẹgẹbi ireti wa.

# OLOYE ESSIEN UDO D'OLOGBE

UYO—Oloye Essien Udo ti o di ẹmọ ogoje ọdun l'aye ni agbọ pe o ku ni ile rẹ ni abule Obio Offot l'agbegbe ilu Uyo nilẹ Ibo.

O'oye Essien yi ni ẹniti o d'agba ju ni agbegbe Uyo. O fi ọmọ bi ọgọrun silẹ l'aiye, ọmọ bibi ati ọmọ-ọmọ.



A GIFT FROM HEAVEN!
BAMWO BABY MIXTURE
OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.
PRICE 2/6 POSTAGE 1/
THE EGBA TRADING ARADAN STORES, 44 DENTON STREET, P.O. BOX 2, EBUTE METTA & BRANCHES

## Ha! Ẹnyin Obi, E roju Ole

(O bẹrẹ loju ewe karun)

Pupọ ninu awọn obi miran ni ọ . . rẹ ti o si nṣe ane, ti yio si ma gbowo lọwọ rẹ, ṣugbọn ti o ba wadi oyun, yio ma a so pe tọ baba rẹ lọ, bẹ nigbati wọn kowo wa fun ọ o gba, tabi nigbati ọmọ rẹ si nko asọ wale, o ko bere ibiti o ti ri, o si ngba owo lọwọ rẹ lai ko bere ibiti o ti ri, o nigbati ki i ṣẹṣẹ o wa di oyun o wa di oyun o wa fa igbe ta.

Mo bẹ ẹnyin iya pupọ, ẹ ye maa bo aṣiri awọn ọmọ yin ni ibo kubo ti ẹ ba ti ri ohun ti ko dara, e sare ki gbe wọn si 'a fun aladugbo yin, ẹ ye gba owo lọwọ wọn, ẹ ma a bere ibiti nwon ba ti ri owo, ẹ ma a ba wọn sọrọ iṣiti pẹlu imọran. Nitori ti ẹ ko ba nhu irafẹ iwa bayi aṣakaṣa yio jẹ ọba lọkan wọn, yio si maa fa pe ki ọmọ odun mejila ma ni oyun papa.

# GOMINA GBOGBO-GBO NI AFIN OBA OYINBO

LONDON - Irohin kan wa lati ilu Oyinbo wipe Ọlọla nla Gomina Gbogbo-gbo, Dokita Nnamdi Azikiwe P.C, ti nwọn fi bura fun oye "Bọbajiro" ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo fi da lọla ni a gbọ wipe o ni anfani lati ba awọn Igbimọ Ab'ọbajiro joko ni Afin ọba ilu Oyinbo ni asiko isinmi rẹ ti o lọ o nilu nla London.



Gomina Agba tun fi ọla rẹ bukun ayẹyẹ ifijoye "Bọbajiro" ti nwọn ṣe fun Alhaji Dokita Sir Abubakar Tafawa Balewa ni ọjọ Alaruba (Wednesday) ọsẹ yi.

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 48, Kosoko Street P. O. Box 407 Lagos Phone 23370